# LASU JOURNAL OF HUMANITIES
# (LASUJOH)

**VOL. 14, 2020 EDITION | ISSN: 978-274-384-4**

*A publication of:*

Faculty of Arts
Lagos State University, Ojo
Lagos, Nigeria.
Email: dean-arts@lasu.edu.ng

# LASU Journal of Humanities
## (LASUJOH)

Volume 14, 2020 Edition

© 2020 Faculty of Arts
Lagos State University, Ojo
Lagos, Nigeria

ISSN: 978-274-384-4

Produced by

FREE ENTERPRISE PUBLISHERS LAGOS

**HEAD OFFICE:** 50 Thomas Salako Street, Ogba,Ikeja, Lagos.
☎+234.814.1211.670.✉free.ent.publishers@gmail.com

FREE ENTERPRISE PUBLISHERS

## EDITORIAL BOARD

| | |
|---|---|
| Editor-in-Chief | Prof. Tayo Ajayi, Dean, Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo, Lagos, Nigeria |
| Editor | Dr. Oseni Taiwo Afisi, Dept. of Philosophy, Lagos State University, Ojo |
| Associate Editor / Secretary, Editorial Board | Dr. Rasaq Thomas, Dept. of Foreign Languages, Lagos State University, Ojo |
| Business Manager | Dr. Abayomi Bello, Dept. of Theatre Arts and Music, Lagos State University, Ojo |
| Managing Editor | Dr. Titilayo Onadipe-Shalom, Dept. of African Languages, Literatures & Communication Arts |
| Members | Dr. Adewunmi Falode, Dept. of History & Int'l. Studies, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Adepeju Johnson Bashua, Dept. of Religions & Peace Studies, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Ayo Ayodele, Dept. of English, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Maruf Animashaun, Dept. of Foreign Languages, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Oseni T. Afisi, Dept. of Philosophy, Lagos State University, Ojo |
| | Dr. Ahmed Adesanya, Dept. of African Languages, Literatures & Communication Arts, Lagos State University, Ojo |
| | Prof. Sola Fosudo, Dept. of Theater Arts & Music, Lagos State University, Ojo |

## EDITORIAL CONSULTANTS

| | |
|---|---|
| Prof. Ihuah Aloysius Shaagee | Benue State University, Makurdi Benue State |
| Prof. I.S. Aderibigbe | University of Georgia, Athens, Georgia USA |
| Prof Rauf Adebisi | Ahmadu Bello University, Zaria Kaduna State |
| Prof. Gbenga Ibileye | Federal University, Lokoja Kogi State |
| Prof. Bode Omojola | Mount Holyoke College, South Hadley, Massachusetts, USA |
| Prof. Emmanuel DanDaura | Nasarawa State University, Keffi Nasarawa State |
| Prof. Antonia Schleicher | Indiana University, Bloomington Indiana, USA |
| Prof. Toyin Falola | University of Texas at Austin, Texas, USA |
| Prof. Mashood Baderin | School of Law University of London, Russell Square London, UK |

## SUBMISSION OF ARTICLES

(Published by the Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo, Lagos, Nigeria), the LASU Journal of Humanities encourages submissions from a variety of theoretical standpoints and from different disciplines—especially those that traditionally belong to the all-encompassing "Faculty of Arts" including, however, other areas with which the Faculty has affiliation: anthropology, cultural studies, folklore, media studies, popular culture, communication, sociology and political science.

## GUIDELINES FOR AUTHORS

- **Articles**

Authors should submit research articles of (maximum) 10-20 A4 pages, double spaced, 12-point Times New Roman type, in accordance with the MLA or APA style, and include an abstract of not more than 100 words and a "Works Cited" section. Authors should email their articles as Microsoft Word (version 97-2000 or later) format attachment to: dean-arts@lasu.edu.ng

- **Journal Flyer/Call For Paper:**

Every article for publication must be accompanied by a processing fee of Ten Thousand Naira only in cash or by cheque payable to the Faculty Wema Bank Account: LASU FAC Arts Research, Publications & Conference Account Number: 0240791717. Please request a receipt or written acknowledgement for all such payments..

- **Illustrations**

If an article is selected for publication, electronic copies of accompanying illustrations, photographs and diagrams must be provided, as well as all necessary captions. Permission to publish images must be secured by the author. Uncompressed JPEG/PDF file (300 dpi resolution) is the preferred format for all electronic copies. Electronic copies must be sent as e-mail attachments to: dean-arts@lasu.edu.ng

- Warning—Footnotes are absolutely prohibited

Journal Address: LASU Journal of Humanities
c/o The Dean, Faculty of Arts, Lagos State University, Ojo
Lagos, Nigeria. e-mail: lasujournalofhumanities@lasu.edu.ng

- Subscription—The Journal is published twice annually although submissions are accepted throughout the year

# Contributors


1. Aande, Simeon Iember
Dept. of Religion & Philosophy,
University of Mkar,
Benue State, Nigeria.

2. Adegbindin, Omotade
Department of Philosophy
University of Ibadan
Ibadan

3. Ajakah, John Chukwuma
Faculty of Humanities, Social &
Mgt. Sciences,
West African Union University
Cotonou, Bénin Republic

4. Apuuivom, Daniel Bem
Dept. of Religion & Philosophy,
University of Mkar,
Gboko, Benue State.

5. Balogun, Badrudeen Adesina
Dept. of Religious Studies
Ekiti State University
Ado Ekiti, Nigeria

6. Bamgbose, Ganiu Abisoye
Dept. of English
Lagos State University
Ojo, Lagos

7. Bamisile, Sunday Adetunji
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University
Ojo

8. Bello, Mufutau Olusola
Dept. of Religious Studies
Ekiti State University
Ado Ekiti, Nigeria

9. Fayemi, Ademola Kazeem
Dept. of Philosophy
University of Lagos
Akoka, Lagos

10. Filani, Ibukun
Augustine University
Epe, Lagos, Nigeria

11. Houenon, Casimir
IBB University Lapai
Niger State

12. Hunjo, Henry Jedidiah
Dept. of English
Lagos State University
Lagos, Nigeria

13. Inyaregh, Abel Aor
Dept. of Religious Studies,
National Open University of
Nigeria,
Jabi, Abuja

14. Loko, Olugbenga Olanrewaju
Dept. of Theatre Arts & Music
Lagos State University, Ojo

15. Macaulay-Adeyelure, Olawunmi
Dept. of Philosophy
Lagos State University, Ojo
Nigeria

16. Ndeche, Chinyere C.
Spiritan University
Nneochi, Abia State

17. Ochiai, Takehiko
Professor in African Studies &
International Relations,
Faculty of Law, Ryukoku
University, Japan

18. Olómù, Oyèwolé Ọlamide
Dept. of African Languages,
Literature & Communication Arts
Lagos State University
Ọ̀jọ́

19. Ọ̀nádípẹ̀–Shalom, Títílayọ̀
Dept. of African Languages,
Literatures & Communication
Arts, Lagos State University, Ojo,
Lagos.

20. Onyemelukwe, Ifeoma Mabel
Dept. of French
Ahmadu Bello University, Zaria,
Nigeria

21. Oye, Adetola Olujare
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University
Ojo, Lagos.

22. Salman, Hakeem
Dept. of Foreign Languages
Lagos State University,
Ojo, Lagos

23. Taiwo, Adekemi Agnes
Dept. of Linguistics & Nigerian
Languages
Ekiti State University
Ado-Ekiti, Nigeria

24. Umah, Paulinus
Federal University of Lafia
Nasarawa State

# Contents


1 "Heaven Helps Only Those Who Help Themselves": Ladipo Solanke and the WASU Hostels in London—Ochiai, Takehiko, . . . . . 1

2 Polygamy and the Rights of Women: Reflections on Religious Feminism —Fayemi, Ademola Kazeem . . . . . 18

3 Beyond Racism: Language Use, Raciolinguistics and the Cognition of Africa —Adegbindin, Omotade, PhD. . . . . . 31

4 Referencing and Academic Integrity and Excellence: An Evaluation —Onyemelukwe, Ifeoma Mabel . . . . . 42

5 A Constructivist Critique of Gene Editing—Macaulay-Adeyelure, Olawunmi . . . . . 53

6 Referring Expressions in Nigerian Stand-Up Contexts—Filani, Ibukun & Bamgbose, Ganiu Abisoye . . . . . 63

7 José Luandino Vieira: Marcas de Africanidade, Inovação E Autenticidade No Texto Literário—Bamisile, Sunday Adetunji, PhD . . . . . 83

8 Analysis of *Gangbe* Music of Badagry Ogu Community, Lagos, Nigeria —Loko, Olugbenga Olanrewaju, PhD . . . . . 95

9 The Fanti Carnival in Lagos and its Message of Morality—Ọ̀nádípẹ̀-Shalom, Títílayọ̀. . . . 106

10 The Life and Times of Musa Ajagbemokeferi: 1933-2000—Bello, Mufutau Olusola, PhD & Balogun, Badrudeen Adesina. . . . . 113

11 Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Èro Yorùbá Nínú Orin Fuji Saheed Ọ̀ṣùpá—Taiwo, Adekemi Agnes . . . . . 125

12 A Study of Lexical Priming in Newton Jibunoh's *Hunger for Power* —Hunjo, Henry J., PhD & Ajakah, John Chukwuma . . . . . 137

13 Fífi àṣà Ìṣèlú tìpá Tìkúùkù yiiri Ìpolongo Ìbo ni Ipilẹ̀ Èkó—Olómù, Oyèwolé Ọlamide . . . . . 156

14 L'Implication de la Theorie du Skopos dans la Traduction des Anthroponymes —Oye, Adetola Olujare, PhD . . . . . 168

15 Traduire le hanló ou la chanson satirique fon en français: Dilemme identitaire, défis et fonctionnalité—Houenon, Casimir & Umah, Paulinus . . . . . 177

16 Conversational implicature and Politics in Achebe's *A Man of the People* —Ndeche, Chinyere, PhD. . . . . . 191

17 Nehemiah's Strategy of Fighting Corruption and Injustice in Neh. 5: 1-19: Implication for Incorruptible and Just Leadership in Nigeria's Democracy—Apuuivom, Daniel B., PhD, Inyaregh, Abel A., PhD & Aande, Simeon I., PhD . . . . . 202

18 Salman, Hakeem, PhD— الموشّحات الأندلسيّة : ثورة فنّيّة اجتماعيّة علي الشعر العربي الكلاسيكي . . . . . 214

# 13

# Fífi àṣà Ìṣèlú tìpá Tìkúùkù yiiri Ìpolongo Ìbo ni Ipilẹ̀ Èkó

*Olómù, Oyèwolé Ọlamide*


## Àṣamọ̀

*Ìpolongo ìbò ní ìlú tí ó gbajúmọ̀ bí Ìpínlẹ̀ Èkó gbòòrò ju orin ìṣẹ̀lú lásán lọ. Ipolongo ìbò bóo ba o pá, boò ba ò buu lẹ́sẹ̀ ni ó gbayé kan, àfàìmọ̀ kómi má tẹ̀yìn wọ ìgbín lẹ́nu nínú ètò ìṣèlú Nàìjíríà ti nnkan ba n lo bayii. Àlàfo tí ó ti ṣí sílẹ̀ nípa àìsí iṣẹ́ tí ò lọ́ọ̀rìn lórí ìpolongo ìbò bóò ba ò pá bòó bà ò bùú lẹ́sẹ̀ àti ọwọ́ yẹpẹrẹ tí àwọn alákadá lórí ìṣèlú fi mú iṣẹ́ lórí ìpolongo ìbò tìpá tikúùkù ni iṣẹ́ yìí di. Ètè ọgbọ́n ìwádìí tí a lò fún àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ yìí ni àyẹ̀wò ìpolongo ìbò tí ó ti wáyé sẹ́yìn ní Ìpínlẹ̀ Èkó láti ọdún 1952 tí Ẹgbẹ́ Òṣèlú ti bẹ̀rẹ̀ títí di ọdún 2019 ni a wo ninu Ìwádìí yìí. Abajade fihan pé kàkà kó sàn lára ìyá àjẹ́, ń ṣe ló ń fi gbogbo ọmọ rẹ̀ bí obìnrin. Tíọ́rì ìjìnlẹ̀ nípa ẹ̀dá àti ìlànà òṣèlú tí a mọ̀ sí Karl Marx (Karl Marx theory) àti tíọ́rì lámẹ̀yítọ́ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ láwùjọ. (Sociological approach/ criticism) ni a fi ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí, tíọ́rì méjèèjì yìí ran iṣẹ́ yìí lọ́wọ́ nítorí àwùjọ ni orin àti ìṣèlú wà fún. Tíọ́rì yìí hàn pé àwùjọ kò ṣe é yà kúrò lára ìṣèlú. Ní ìkádìí, iṣẹ́ yìí fi hàn pé ètò ìpolongo ìbò ń fẹ́ àmójútó tí a bá fẹ́ kí ètò ìṣèlú wa máa gbilẹ̀ sí tí a ó lè fi apeere tí ó ṣe é fi yangàn sílẹ̀ fún ọjọ́ ọ̀la ti ètò ìṣèlú tí yóò mú kí ìdàgbàsókè bá ilẹ̀ wa gbooro sii.*


***Kókó ọ̀rọ̀:*** *àsà ìṣẹ̀lú, Ìpínlẹ̀ Èkó, ìpolongo ìbò, ìtòrò àwùjọ, tìpá tikúùkù*

## Ìfáàrà

Gbogbo ẹgbẹ́ òṣèlú ni ó ni ọ̀nà àràmàndà tí ń gbà polongo ìbò fún ará ìlu, a lè fi wé ọ̀nà tí òǹtajà ń gbà lo ọgbọn àrékérekè láti ti ọjà mọ́ òǹrajà lọ́wọ́. Ní ọdún 2015, ẹgbẹ́ òṣèlú All Progressives Congress tí a mọ̀ sí APC lo gbogbo ète tí ó wà ní ìkáwọ́ wọn láti rí i pé wọ́n jáwé olúborí mọ àwọn ẹgbẹ́ alátakò yòókú lọ́wọ́ ní Ìpínlẹ̀ Èkó.

Àtubọ̀tán ẹgbẹ́ òṣèlí yìí nínú akiitiyan wọn jẹ́ ohun tí ó yàtọ̀ gedegbe nínú ìgbésẹ̀ ètò òṣèlú ní Ìpínlẹ̀ Èkó àti orílẹ̀ èdè Nàìjíríà.

Ṣíṣe àgbéyẹ̀wò ìpolongo ìbò ẹgbẹ́ òṣèlú yìí yóò fún wa ni àǹfààní tí ó péye láti mọ àléébù oríṣìíríṣìí tí ó jẹ yọ nínú ìpolongo ìbò ọdún 2015 ati 2019. Ẹgbẹ́ òṣèlú All Progressive Congress tiraka láti má jẹ́ kí ìlú Èkó bọ́ lọ́wọ́ wọn nítorí pé omi ti tẹ̀yìn

wọ̀gbín lẹ́nu ní àwọn ìpínlẹ̀ yòókù tí ó jẹ́ ti àwọn ẹgbẹ́ Afẹ́nifẹ́re ní àwọn ìpínlẹ̀ tí ó wà ní Ìwọ̀ Oòrùn. Ẹgbẹ́ yìí lo gbogbo ọ̀nà láti jáwé olúborí láì kọ nǹkan tí yóò le ṣẹlẹ̀.

Pàtàkì iṣẹ́ yìí lápàapọ̀ ni láti ṣe àyẹ̀wò ọ̀nà tí ẹgbẹ́ òṣèlú All Progressive Congress gba polongo ìbò, bí wọ́n ṣe gbégbá orókè àti àtubọ̀tán ìbò náà.

Ǹ jẹ́ ọ̀na tí wọ́n fi wọlé ṣe àkóbá fún ètò ìdìbò ọjọ́ iwájú? Ẹ̀kọ́ wo ni a tilẹ̀ le rí kọ́ nínú ìpolongo ìbò ẹgbẹ́ òṣèlú yìí? Gbogbo ìbéèrè wọ̀nyí ni iṣẹ́ yìí yóò ṣe ọ̀rínkínníwín àlàyé lórí rẹ̀.

## Èrò Yorùbá lórí Ìpolongo?

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ìpolówó àti ìpolongo ni àwúre ọjà títà, kín ni ìpolongo? Ìpolongo jẹ́ ọ̀nà tí à ń gbà láti sọ́ di mímọ̀ pẹ̀lú èróńgbà láti ta ọjà àti iṣẹ́ ẹni.

Lọ́nà mìíràn "Ìpolongo jẹ́ ọ̀nà tí à ń gbà láti pe àkíyèsí ara ìlú si ohun kan tabi omiran láì ṣe làálàá pẹ̀lú owó pọ́ọ̀kú."

Tí a bá bá ọ̀nà tí ìtúpalẹ̀ ìpolongo àkọ́kọ́ wọ̀ ó, a ó ri dájú pé ìpolongo ní í ṣe pẹ̀lú ọjà títà tàbí rírà. Bí ilé-iṣẹ́ kan bá ṣe ọjà kan síta, ó pọn dandan fún ilé-iṣẹ́ náà láti sọ ọjà náà di mímọ̀ fún ará ìlú, kí ọjà náà lè yá lórí igbá. Bákan náà ni ti ọ̀jọ̀gbọ́n kan bá gbé èróńgbà kan kalẹ̀, dandan ni kó wá ọ̀nà tí èróńgba rẹ̀ náà yóò ṣe di mímọ̀, ó wá jẹ́ pé dandan lowó orí lọ̀rọ̀ ìpolongo nínú ọjà títà. Fún ìdí èyí, a rí i dájú wí pé ìpolongo ń làkàkà láti ta ọjà, iṣẹ́ ẹni tó ní èròńgbà náà.

Tí a bá fi òṣùwọ̀n àtúpalẹ̀ ìpolongo ẹlẹ́ẹ̀kejì wò ó, a ó rí wí pé ìpolongo gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí yóò múni lọ́kàn tí a bá ti gbọ́ ọ tàbí rí i kà, láti tẹ̀lé ípolongo náà, èyí yóò múni ra ọjà tàbí gbàgbó pé kò sí nǹkan mìíràn tó dára jù ú lọ.

Fún àpẹẹrẹ: Ìpolongo Ọtí "Seaman's Schnapps" tí ó sọ wí pé:

Ọtí Ìsẹ̀nbáyé

Ọtí tó ta wọn yọ níbi ayẹyẹ gbogbo

Ọtí àwọn àgbà

Àgbà àwọn Ọtí

Tí a bá wo irúfẹ́ ìpolongo yìí, a ó rí i wí pé ó fani mọ́ra, nígbà tí wọ́n ní "Ọtí ìsẹ̀nbáyé" ni, èyí ni pé ọtí yìí ti wá láti ọdún pípẹ́, wọ́n tún ní "ó ta wọn yọ níbi ayẹyẹ gbogbo" èyí ni pé kò sì ayẹyẹ kankan tí wọn kò lè lò ó fún, wọ́n tún ní "ọtí àwọn àgbà, àgbà àwọn ọtí" èyí fihàn pé àwọn àgbààgbà nífẹ̀ẹ́ sí ọtí náà àti pé ọtí náà làgbà gbogbo ọtí pátá. Ìpolongo yìí yóò múni ra ọtí yìí láìṣe iyèméjì.

Fún àpẹẹrẹ mìíràn, ìpolongo ẹgbẹ́ òṣèlú kan "Alliance for Democracy" ìyẹn ẹgbẹ́ afẹ́nifẹ́rẹ, ìpolongo náà lọ báyìí:

Ẹ dìbò fún Ẹgbẹ́ Afẹ́nifẹ́re (AD)

Ẹgbẹ́ kan ṣoṣo tó ṣe é tẹ̀lé

Tó ṣe é fọkàn tán fún ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́

Ìwòsàn ọ̀fẹ́, ìdàgbàsókè nígbèríko

Ìdáàbòbò àyíká

Yíyí ipò agbára padà

Irúfẹ́ ìpolongo yìí pàápàá, àwọn nǹkan amáyédẹrùn tí wọ́n pè ní "Ọ̀fẹ́" yóò jẹ́ kí àwọn olùgbọ́ àti olùdìbò dìbò fún ẹgbẹ́ náà láì wẹ̀yìn wò.

## Ìpolongo Láyé Àtijọ́

Ní ayé átijọ́, àwùjọ kéré tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ tó jẹ́ pé ṣugutu-ṣugutu ni abà àti ìletò wà.

Síbẹ̀ náà, ètò ìpolongo ń wáyé láàárìn àwọn ènìyàn ìgbàà-ni, fún àpẹẹrẹ, àwọn ènìyàn bí àgbẹ̀ tàbí oníṣẹ́-ọnà mìíràn máa ń kó ohun tí wọ́n ní fún títa síi agbègbè tí ó bọ́ sí ojú-táyé láti lè jẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ irúfẹ́ ohun tí wọ́n ní fún títà. Wọn yóò sì fi iye òkuta kan sí ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ fún iye owó ọjà náà.

Bákan náà ẹ̀wẹ̀, kò sí àwọn ohun èlò tí a lè lò láti fi ṣe ìpolongo tó dáńgájíá. Erédìí èyí ni pé ọ̀làjú jìnnà sí wọn lákòókò náà, fún àpẹẹrẹ, nígbàkúgbà tí ẹnikẹ́ni bá fẹ́ ṣe ìpolongo nǹkan ní pàtó, wọ́n lè fọn fèrè tàbí kí wọ́n lu agogo tàbí ìlù láti kó ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ èèyàn jọ láti fi èrò inú wọn hàn nípa ohun titun tàbí àyípadà ti fún àwùjọ wọn. Fún àpẹẹrẹ ti baálé abúlé bá ní èrò kan láti sọ di mímọ̀ fún àwọn ènìyàn rẹ̀, yóò ran aláago síta láti lù ú yíká abúlé pàápàá, ní ààrìn ọjà abúlé tí yóò kéde, èyí tí àwọn èrò ọjà náà yóò lọ tàn kalẹ̀ tí wọ́n bá lọ sí ilé wọn.

## Ìpolongo Òde Òní

Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ wí pé tí àwùjọ ti gbòòrò tí ó sì ti kọjá tàná, ọ̀làjú sì ti wọlé dé onírúurú ọ̀nà ni àwọn ènìyàn ń gbà láti polongo ohun yòówù tí wọ́n bá ní tàbí gbé èròńgbà wọn jáde nípa ohun kan pàtó, oúnjẹ, aṣọ, ohun ẹ̀ṣọ́-ilé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ lọ. Lónìí, oríṣìíríṣìí ètò ìgbékalẹ̀ ni ó ti wà pẹ̀lú ètò àwọn èrò amúṣẹ́yá ìgbàlódé.

Lódè òní, ìpolongo ń wáyé lórí ẹ̀rọ rédíò, tẹlifísàn, lórí ìwé ìròyìn pàápàá nínú àwọn ìwé ìléwọ́ tí àwọn òǹtẹ̀wé ń tẹ̀ jáde pẹ̀lú àwọn àwòrán tó fanimọ́ra lóríṣìíríṣìí àwọ̀, ẹ̀rọ ayélujára òde òní pèsè abala lóríṣìíríṣìí ara láti gbé ohùn àti àwòrán sí orí afẹ́fẹ́ ní ìrọ̀rùn.

## Ìwúlò Ìpolongo

Ìpolongo àti ìpolówó bí ó ti wúlò tó síbẹ̀ náà, kìí ṣe gbogbo ilé-iṣẹ́ pátá ló nílò rẹ̀ fún àpẹẹrẹ àwọn panápaná, ọlọ́pàá, àwọn iṣẹ́ ológun àti ilé ìwòsàn, àyàfi iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan tí wọ́n bá fẹ́ gbààyàn ṣíṣẹ́.

Dandan ni kí ìpolongo wà bí ọ̀nà eré ìtàgé àti kí wọ́n máa ṣe àpọ́nlé tayọ bó ṣe yẹ, kí àwọn ènìyàn lèrà tàbí gbọ́ ìpolongo wọn.

> Ìpolongo ti ní àwọn ènìyàn tí a dojú rẹ̀ kọ gan-an.
>
> Ìpolongo wúlò gan-an láti ran ilé-iṣẹ́ tàbí ẹgbẹ́ lọ́wọ́ láti ta ọjà rẹ̀ tàbí sọ iṣẹ́-ọnà di mímọ̀.

## Orin Nínú Ìpolongo

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti fi ìmọ̀ wọn hàn lórí ohun tí orin jẹ́ lára wọn ni Délànọ̀ (1958), Finnegan (1970), Ọlájubú (1981:2), Olúkojú (1985:125), Ilésanmí (1986), àti Olúnládé (1998). Délànọ̀ (1958) oun túmọ̀ orin sí ohùn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tí ó dùn.

Ẹwà ọ̀rọ̀ tí wọ́n máa ń lò nínú orin ni ó jẹ Délànọ̀ lógún jù nínú ìtumọ̀ tó fún

orin. Ọlájubú (1981:2) gbà pé orin jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwọn ènìyàn fi máa ń fi èrò ọkàn wọn hàn.

Olúkojú (1985:125) sọ pé orin kíkọ ni ọ̀rọ̀ àsọ̀sọtán ní ọ̀nà tí ó mú kí ọ̀rọ̀ wọ ni lára. Oríkì tí Olúkojú fún orin jẹ́ kí a mọ ìyàtọ̀ láàárin ọ̀rọ̀ geere àti orin. Olúkojú ló jẹ́ kí á mọ̀ pé orin máa ń ní àfàgùn àwọn sílébù kan bí "e e e," a o," "o o o o," "e o." àpẹẹrẹ orin tí kò ní ègbè tí a sì tún rí ìwéhùn tí a wí yìí rí bí i orin tí àwọn onílù fi ń ki oríkì ènìyàn, láti fi yìn ín tàbí fi pọ́n ọn lé yálà lágbo ijó ní o tàbí nínú àwọn rékọ̀ọ̀dù. Àpẹẹrẹ orin tí onílù gbajú-gbajà kan kọ lọ́dún díẹ̀ sẹ́yìn ni kò ní ègbè orin nínú:

Ọmọ pupa o o o o o
Ọmọ pupa làwa ń fẹ́ ẹ́ ẹ́
Ọmọ pupa o o o o o
Jọ̀wọ́ kò bọ́kọ dé o o o…

Yàtọ̀ sí ọ̀nà àpọ́nĺé àti àyẹ́sí tí Yorùbá ń gbà lo orin, wọ́n tún ń lò ó ní ọ̀nà èébú, ọ̀tẹ̀, àbùkù àti ìbàjẹ́. Ọ̀nà tí àwọn olóṣèlú ń lo orin ọ̀tẹ̀ láwùjọ ni ó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ yìí, a ó sísọ lójú rẹ̀.

## Ìbẹ̀rẹ̀ Ìpolongo ìbò ní Ìpínlẹ̀ Èkó

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣíwájú, ìpolongo ìbò ti bẹ̀rẹ̀ láti ìgbà tí ènìyàn méjì, mẹ́ta, mẹ́rin tàbí ju bẹ́ẹ̀ lọ bá ti wà ní ibìkan tí wọ́n sì ń fẹ́ ìlọsíwájú fún ará, ìwádìí fi yé wa pé láti ìgbà tí a ti ń fẹ́ ìlọsíwájú fún ìdàgbàsókè ara wa yìí ni ìpolongo ìbò ti bẹ̀rẹ̀. Ẹ̀rí tí ó dájú mìíràn fi yé wa pé ọdún 1963 nígbà tí àwọn ènìyàn ń díje fún ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin tí wọ́n yan aṣojú ní Ìpínlẹ̀ Èkó lóríṣìíríṣìí ni ìpolongo ìbò túbọ̀ ń gbilẹ̀ sí i.

Ní ọdún 1967 wàyìí, dídá tí a dá ìjọba Ìpínlè Èkó sílè, iná ìpolongo ìbò túbọ̀ sí ní ràn sì i.

Yàtọ̀ sí èyí, ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkó gẹ́gẹ́ bí olú ìlú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà lẹ́yìn ìgbà tí a gbé kúrò ní ìlú Calabar wà jẹ ìlú tí ó lókìkí tí oríṣìíríṣìí ètò ìṣèlú tí ń wáyé pàápàá jùlọ ní àsìkò ìjọba alágbádá àkọ́kọ́ (First Republic).

Ní àsìkò yìí, oríṣìíríṣìí ẹgbẹ́ òṣèlú ni ó fi Èkó ṣe olú ilé ẹ̀ka ìpolongo ìbò wọn. Lára àwọn ẹgbẹ́ tí ó lókìkí nígbà náà ní agbègbè ìwọ̀ oòrùn ni Action Group (AG) tí olóògbé Ọbáfẹ́mi Awólówò, (National Council of Nigeria and Cameroon) (NCNC) ti àríwá Nàìjìríà. Ṣùgbọ́n ẹgbẹ́ òṣèlú méjéèji ìyẹn Action Group àti National Council of Nigeria and Cameroon (NCNC) ni ó lórúkọ ní ìwọ̀ oòrùn.

Ìpolongo ìbò tí wọ́n ṣe ní Ìpínlẹ̀ Èkó jẹ èyí tí ó ṣe pàtàkí gidigidi nítorí pé ó la ojú ọ̀pọ̀ ènìyàn sí ohun tí à ń pè ní ìṣèlú nípa kíkọ oríṣìíríṣìí orin òṣèlú.

Láàárìn ìjọba ẹgbẹ́ NCNC sí ẹgbẹ́ Alákùkọ àti Ẹgbẹ́ AG tí a mọ̀ sí Ọlọ́pẹ ni owú jíjẹ òṣèlú ti bẹ̀rẹ̀. Lára àpẹẹrẹ orin tí àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú wọ̀nyí fi ń ṣáátá ara wọn nígbà náà ni:

Inú igbó lọ̀pẹ ń gbé
Inú igbó lọ̀pẹ ń gbé
Ẹ̀nìkan kìí kọ́lé adẹ́tẹ̀ sígboro
Inú igbó lọ̀pẹ ń gbé

Àwọn ẹgbẹ́ òsèlú Action Group tí ó jẹ́ ẹgbẹ́ Ọlọ́pẹ náà lè dáhùn pé:

Awólọ́wọ̀ ìwọ la rí báwí
Awólọ́wọ̀ ìwọ la rí báwí
Ìwọ tí o mọ́bẹ lọ́wọ́ tó ò le pàkùkọ
Awólọ́wọ̀ ìwọ la rí báwí

Awólọ́wọ̀ yìí ni olórí ẹgbẹ́ Ọlọ́pẹ, ṣe ẹran jíjẹ sì ni àkùkọ tí ó jẹ́ àmì ẹgbẹ́ wọn. Gbogbo àwọn akitiyan wọ̀nyìí wà lára nǹkan tí ó má ń jẹ́ ìpolongo ìbò dùn ní ìpínlẹ̀ Èkó, lákòótán, kó si ètò kan tí wọ́n lè ṣe nípa òṣèlú nígbà náà tí Ìpínlẹ̀ Èkó kò kó ipa pàtàkì nínú rẹ̀, ìpolongo ìbò tí ó wà la gbogbo ènìyàn lójú ní ìlú Èkó gan-an ni ìpolongo ìbò ti ọdún 1979/1980 ní ìgbà ayé ìjọba alágbádá ẹlẹ́ẹ̀kejì.

Ní àsíkò yìí ni Ọ̀gágun Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́ fẹ́ gbé ìjọba sílẹ̀ fún àwọn olóṣèlú.

Ìpolongo ìbò yìí jẹ́ mánigbàgbé ní Ìpínlẹ̀ Èkó nitorí pé ó jẹ́ Ìpínlẹ̀ tí à ń gbà polongo ìbò lónìí gùn lé, tí ó jẹ́ wí pé wíwọlé tipátipá ní ọ̀nà tí gbogbo olóṣèlú ń tọ̀.

Ọ̀pọ̀ ẹ̀mí ni ó ṣòfò, dùkìá tí ó sègbé kò níye síbẹ̀ ẹ̀rí àti àbájáde ìbò yìí fi hàn pé wọ́n gbé ọmọ ọba fún Ṣọ̀ún ni ìdìbò olórí orílẹ̀ èdè ṣùgbọ́n ní Ìpínlẹ̀ Èkó mìmì kan ò mí Ẹgbẹ́ tí wọ́n yàn láàyò ìyẹn Ẹgbẹ́ Òṣèlú Unity Party of Nigeria (UPN) lásìkò yìí ni Alhaji Lateef Jákandè wọlé gẹ́gẹ́ bí gómìnà Ìpínlẹ̀ Èkó.

Lára àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú tí ó polongo ìbò nígbà náà ní ìlú Èkó ni Ẹgbẹ́ Onílé (NPN), Ẹgbẹ́ Ìmọ́lẹ̀ (UPN), NPP (Nigeria People Party), NAP (Nigeria Adgbanced Party), PRP (People Redemption Party), NPP (Great Nigeria People Party). Kódà ẹgbẹ́ òṣèlú gbajúgbajà olórin Afro ni, Fẹlá Aníkúlápó Kútì Masses Movement tí awuyewuye wà lórí bóyá wọn forúkọ rẹ̀ sílẹ̀ àbí wọ́n gbà á láàyè kó forúkọ sílẹ̀. Ẹgbẹ́ òṣèlú yìí náà polongo ìbò káàkiri ní ìlú Èkó.

## Ọgbọ́n Ìwádìí

A lọ káàkiri ọ̀dọ̀ àwọn olóṣèlú ní Ìpínlẹ̀ Èkó, a lọ àwọn ilé ìkàwé àwọn Yunifásítì Èkó, Ilé Ẹ̀kọ́ Olùkọ́ Àgbà Ẹn.Síì. a fi ọ̀rọ̀ wa àwọn olùdìbò lẹ́nu wò, kódà a dé ọ̀dọ̀ àwọn bàbá ìsàlẹ̀ ẹgbẹ́ ní ìjọba ìbílẹ̀. A sì tún fi ọgbọ́n gbọ́ tẹnu àwọn tí wọ́n ń lọ fún jàndùkú. Gbogbo ìwé ìròyìn àti iṣẹ́ tó jẹ mọ́ṣẹ́ wa tí ó wà lárọ̀wọ́tó wa ni a kà. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, a tẹ àwọn olóṣèlú níkùn dáadáa, wọ́n sì sọ nǹkan tí ó wúlò fún iṣẹ́ yìí fún wa.

## Tíọ́rì tí a lò Fún Àyẹ̀wò Lítíréṣọ̀

Kí á tó wo tíọ́rì àyẹ̀wò lítíréṣọ̀, ó yẹ kí á mọ nǹkan tí à ń pè ní lítíréṣọ̀ gan-an.

Kín ni Lítíréṣọ̀ fúnra rẹ̀? Ìtumọ̀ lítíréṣọ̀ kò dúró ṣójú kan, ó máa ń yí padà láti ìgbà dé ìgbà àti ọ̀dọ̀ ẹ̀yà kan sí èkejì. Láti inú èdè Látìnì ní lítíréṣọ̀ ti jẹ jáde "Litera" èyí túmọ̀ sí ọ̀rọ̀ tí a fi lẹ́tà kọ ohùn ní Gẹ̀ẹ́sì sọ di lítíréṣọ̀. Èyí túmọ̀ sí ọ̀rọ̀ tí a kọ sínú ìwé. Lítíréṣọ̀ jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ayé, kò rọrùn fún ẹnìkan láti rí kúlẹ̀kúlẹ̀ lítíréṣọ̀ lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo nítorí pé ibi tí ẹnìkan bá rí lítíréṣọ̀ mọ náà ni yóò ṣàlàyé rẹ̀ mọ.

Lítíréṣọ̀ dálé ìgbé ayé ọmọ ènìyàn tàbí ìṣẹ̀dá ayé, lítíréṣọ̀ fi ayé yé ni, ó sì fún ni ní ìmọ̀, ó máa ń kún fún àwọn ẹwà èdè tó dùn mọ́ni, tó fara mọ́ni tí ó sì ń fún

ni ní ìtẹ́lọ́rùn ní ọ̀nà tí à ń gbà gbé e jáde. Lítíréṣọ̀ dálé adùn pàtàkì tí ó ṣọ̀wọ́n jùlọ nípa ipò ẹ̀kọ́ mìíràn.

Lítíréṣọ̀ jẹ́ àkójọpọ̀ oró yálà alákọsílẹ̀ tàbí aláfẹnupè tó gbọgbọ́n nípa orísìírísìí ìrírí ènìyàn nípa ilé ayé tí a gbé kalẹ̀ pẹ̀lú àrogún àti àròjinlẹ̀. Èyí wá lè jẹmọ́ ohun tó jẹ ọmọ ènìyàn lójú àti ohun mìíràn tí ó ṣe ọkàn ọmọ ènìyàn ní kúṣú nípa ilé ayé.

Gẹ́gẹ́ bí Ayọ̀ Ọpẹ́fẹ̀hìntìmí (1977) nínú ìwé rẹ̀ tí o kọ lórí *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lo-Èdè*, ó ṣàlàyé lórí oríkì lítíréṣọ̀ ṣíwájú sí i, ó ní "lítíréṣọ̀ ni ohun yòówù tí ó bá lákọ̀ọ́lẹ̀." Ṣùgbọ́n nínú àríwísí tsèmi, lítíréṣọ̀ pààlà sí ọ̀nà méjì ọgbọọgba, lítíréṣọ̀ alóhun àti lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ. Àwọn ìtán, ewì tàbí eré-oníṣe tí a fi ohùn dídùn ké jáde ni lítíréṣọ̀ alóhun nígbà tí ìtàn Àròsọ, ewì, tàbí eré-oníṣe tí a pilẹ̀ kọ sílẹ̀ jẹ́ lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ. Kó di ìgbà tí ènìyàn bá kọ nǹkan tó sọ lẹ́nu sílẹ̀ kó tó di lítíréṣọ̀." Èyí ni pé gbogbo àkọ̀ọ́lẹ̀ ìtàn, ìwé ẹ̀rọ tí í dùn bí í ọ̀sanyìn àti ìwé tí ó bá fara pẹ́ wọn jẹ́ lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ nítorí pé a fi lẹ́tà alífábẹ́ẹ̀tì kọ wọ́n sílẹ̀. Lóòótọ́, a lè máa kọ wọ́n gẹ́gẹ́ bí lítíréṣọ̀ ní ilé ìwé, lítíréṣọ̀ ní iṣẹ́ òǹkọ̀wé àtinúdá kan tàbí iṣẹ́ tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìlo ojú inú gẹ́gẹ́ bí ewì, ìtàn, àròkọ tàbí eré oníṣe. Pípọ̀ nínú àwọn nǹkan tí a dárúkọ yìí kó ipa púpọ̀ nínú ìmọ̀ ìgbé ayé ẹ̀dá láwùjọ mọ́ra, ìjálá a kọ ọ́ sílè, a rò ó sọ tàbí a ṣe é léré yàtọ̀ fún àwọn àkọ̀ọ́lẹ̀ iṣẹ́ ọwọ́. Lítíréṣọ̀ máa ń fi ìṣèṣe àti àṣà àgbáríjọ àwọn ènìyàn kan hàn, ó ní ẹwà nínú àbùdá rẹ̀. Èdè tí a ṣe lọ́nà ní lítíréṣọ̀ bí àpẹẹrẹ, àwítúnwí.

Ara àwọn àkọ̀ọ́lẹ̀ wa la pè ní lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ bí i ìtàn àròsọ àti eré oníṣe. Orísìí lítíréṣọ̀ kejì ni a mọ̀ sí lítíréṣọ̀ alóhun, èyí ni ìtàn àròsọ tí ó jẹ́ ìtàn ewì tàbí eré oníṣe ìbílẹ̀. A máa ń ṣe wọ́n ní àbùdá tiwọn, ó lè jẹ́ ìṣòro kéwì bí i ìtàn, ìwúre àti àyájọ́ tàbí ìsáré bí i ẹ̀sà egúngún, òòṣà pípè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Yàtọ̀ fún gbogbo àwọn nǹkan tí a dárúkọ yìí, lítíréṣọ̀ alóhun ni ọ̀rọ̀ tí ó máa ń jẹ jáde láwùjọ Yorùbá tí a bá ń parí ìjà lágbóolé tàbí láàárìn ìgbìmọ̀ ìlú. Èyí ni gbogbo nǹkan tí ó jẹ mọ́ àṣà àti ìṣe Yorùbá tí ó wà lákòónú.

## Tíọ́rì Àmúlò

Tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé pọ̀ wo lítíréṣọ̀ fífi ojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ṣe àtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ ní ọ̀pá òdiwọ̀n fún àyẹ̀wò tí a fi ṣe iṣẹ́ yìí. Àwọn onítíọ́rì yìí gbà pé lítíréṣọ̀ àti ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ kì í ṣe àjòjì ara wọn, ọmọ ìyá kan ni wọ́n, ìdí ni pé èèyàn àti ìrírí èèyàn, ìbágbépọ̀ èèyàn àti àtubọ̀tán rẹ̀ ni wọ́n ń wádìí tí a bá fẹ́ wádìí ìjìnlẹ̀ nípa àwùjọ àti ẹ̀dá inú rẹ̀ soṣiọ́lọ́jì àti lítíréṣọ̀ ni a lè pè yanjú irú ìṣòro tí ó bá dojúkọ, ìdí nìyí tí Hosgart (1966) ṣe sọ pé láìsí ẹ̀rí kíkan àwọn ọmọ iṣẹ́ àtinúdá, ẹ̀rí àwọn tí ó ń kọ nípa àwùjọ kò tíì lé kan tó, ṣosiọ́lọ́jì jẹ mọ́ gbogbo ìṣẹlẹ̀ tí ó bá jẹ mọ́ ọmọnìyàn àti ìbáṣepọ̀ láàrín wọn ohun tí ó jẹ́ ṣosiọ́lọ́jì lógún ní ìgbé ayé ẹ̀dá nínú àwùjọ, ìgbàgbọ́ rẹ̀, àssà rẹ̀, ìwà rẹ̀, èdè rẹ̀ tí ó jẹ́ òpómúléró fún ìdúró ẹ̀dá láyé.

Clandwell (1977:15) ki ṣoṣiọ́lọ́jì báyìí: "At one time men are doing different thing and therefore stand in relation to one another. The study of these human relation in a general form is sociology" (Nígbà kan rí, àwọn ènìyàn máa ń bára wọn ṣe nǹkan pọ. Ìmọ́ lórí ìbára-ẹni-ṣe-pọ̀ yìí ní ọ̀nà onírúurú ni ṣoṣiọ́lọ́jì), ọ̀nà ìbara-ẹni-sọ̀rọ̀ ní lítíréṣọ̀ jẹ́ ó lè wádìí nípa ìhùwàsí láwùjọ.

Tíọ́rì Karl Marx àti àwọn ẹlẹgbẹ́ tẹpẹlẹ mọ́ ọ pé ọwọ́ àwọn ẹ̀dá kan ló ní àṣẹ

lọ́wọ́ láwùjọ tí wọ́n sì ń fi ń jẹ gàba lórí àwọn ọwọ́ ẹ̀dá tí ó kù. Gígàba nípa ọrọ̀-ajé àti ìṣèlú múmú láyà tíọ́rì Karl Marx, ó gbà pé àparò kan kò yẹ kó ga jù ọ̀kan lọ. Ìyípadà tàbí ìfòpinsí ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni ó sáábà máa ń gún àwọn òǹkọ̀wé ní kẹ́sẹ́ láti fi ṣée ọnà wọn hàn fún àwùjọ. Àwọn Karl Marx gbà pé ọrọ̀-ajé ni ó bí ọ̀rọ̀ ìṣèlú. Owó ni a fi ń ṣèlú ọrọ̀-ajé lè wá láti dípò fún ìṣèlú, ọrọ̀-ajé àti ìṣèlú ni ó ṣe atọ́nà fún ìbágbépọ̀ ẹ̀dá. Àṣà, ẹ̀sìn àti ọrọ̀ ajé nì ẹ̀dá ń fi ìrònú lítíréṣọ̀ gbígbé jáde.

## Oríṣìíríṣìí Ọ̀nà Tí Ẹgbẹ́ Òṣèlú Fi Polongo Ìbò

### a. Ìlo Baba Ìsàlẹ̀

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọo ṣíwájú, ìlo baba ìsàlẹ̀ kò ṣe é fọwọ́ ró sẹ́yìn nínú ìṣèlú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Yàtọ̀ sí Olóyè Bísí Àkàndé tí ó jẹ́ alága gbogbogbòò ẹgbẹ́, Senetọ Bọ́lá, A.Tinúbú ni ó dúró digbí gẹ́gẹ́ bí bàbá ìsàlẹ̀ tí ó ń fi ní sípò ní Ìpínlẹ̀ Èkó eléyìí sì hàn gedegbe sí gbogbo ará ìlú nítorí pé gbogbo ibi tí onudíjé bá ń polongo ni Tinúbú ń tẹ̀lé tí ó sì ń fà á lọ́wọ́ sókè pé òun ni kí gbogbo ènìyàn dìbò fún.

Yíyan ondíje Babájídé Sanwó-Olú gan-an gẹ́gẹ́ bí olùdíje ẹgbẹ́ lọ́wọ́ baba ìsàlẹ̀ nínú nítorí pé ọ̀nà tí wọ́n fi yọ Àḿbọ̀dé mú ìfura lọ́wọ́.Tinúbú fúnrarẹ̀ ni ó wá á ri ti ó fà á kalẹ̀ nítorí pé a gbọ́ pé wọlé wọ̀de rẹ̀ ni lọ́jọ́ tó ti pẹ́.

Yàtọ̀ sí èyí lilo Sẹ́nétọ̀ Adéṣẹ̀yẹ Ògúnlẹ́wẹ̀ láti gbógun ti Ìpínlẹ̀ Èkó nígbà tí o wà lórí àléfà ìjọba àpapọ̀ fihàn pé ìjọba àpapọ̀ ni ó dúró gẹ́gẹ́ bí baba ìsàlẹ̀ fún ẹgbẹ́ òṣèlú PDP náà láye Ọbásanjọ́.

Àtẹ̀jáde àwọn ìwé ìròyìn ìṣàle yii yìí fihàn pé ìjọ̀ba àpapọ̀ gbógun ti ìlú Èkó nítorí àti gba Èkó lọ́wọ́ ẹgbẹ́ òṣèlú Action Congress.

> **LASTMA not for federal roads – Ògúnlẹ́wẹ̀.**
>
> [Àwọn Ẹ̀ṣọ́ Ìrìnà Ojú pópó kò wà fún ọ̀nà Ìjọba àpapọ ]
>
> [Withholding the money of local council is wrong. The Federal Government has no right or power to do so… the president has ground to withhold the fund because the state can create new local councils. The states have the right to do so… on moral grounds, it is very bad for the president to withhold the money; it is punishing the innocent – Lateef Jákándè, former Governor, Lagos State.](*The Guardian*, Thursday July 22, 2004, p.8)
>
> Gbígbésẹ̀lé owó àjẹmọ́nú ijọba ìpínlẹ̀ kò tọ̀nà rárá, ìjọba àpapọ̀ kò ní ẹ̀tọ́ tàbí agbára láti ṣe bẹ́ẹ̀… Ààrẹ rí ààyè láti ṣe bẹ́ẹ̀ nítorí pé ìjọba ìpínlẹ̀ dá ìjọba ìbílẹ̀ sílẹ̀. Ìjọba ìpínlẹ̀ ní ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin láti dá ìjọba ìbílẹ̀ sílẹ̀, ó ké ohun tí ó burù jáì fún Ààrẹ orílẹ̀ èdè láti gbẹ́sẹ̀ lé owó náà, ó dàbí a kan ǹ mọ̀ọ́mọ̀ fi ìyà jẹ aláìṣẹ̀.
>
> But by laboring to strangulate the state through non-release of statutory fund to the local governments and by withholding refund of money spent for works earlier done on behalf of a negligent federal government, Ògúnlẹ́wẹ̀ and those he purports to be working for are shooting themselves in the legs.—Sọ́jí Ọmọ́túndé. (*ThisDay*, Thursday July 1, 2004, p.18)
>
> [Ṣùgbọ́n akitiyan láti gbé ẹrù tí ó wúwo ru Ìpínlẹ̀ Èkó nípa láti má yọ̀nda

owó ìṣètò ìjọba ìbílẹ̀, àti láti má a san owó tí ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkó ná lórí àtúnṣe iṣẹ́ ìjọba àpapọ̀, Ògúnlẹ́wẹ̀ àti aẁọọ tí ó rò pé òun ń ṣiṣẹ́ fún n ṣe ara wọ].

Gbogbo ẹ̀rí wọ̀nyí fi hàn gbangba pé ìjọba àpapọ̀ lábẹ́ Ọbásanjọ́ dúró gẹ́gẹ́ bí bàbá ìsàlẹ̀ fún ẹgbẹ́ òṣèlú PDP láti gba ìlú Èkó ní ọdún 2007 nípa lílo Ògúnlẹ́wẹ̀ àti Bọ̀dé George.

**b. Ìlò Ẹ̀rọ Ìgbàlódé Fún Ìpolongo**

Yàtọ̀ sí ìpolongo ojúkorojú tí ẹgbẹ́ òṣèlú Action Congress polongo ní Ìpínlẹ̀ Èkó, wọ́n lo àwọn ẹ̀rọ ìgbàlódé bí i rédíò, tẹlifísàn, ẹ̀rọ ayélujara (internet), ẹro ìbánisọ̀rọ̀, ìwé ìròyìn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gẹ́gẹ́ bí ìjọba tí ó wá lórí àléèfà lásìkò ìdìbò yìí, ilé iṣẹ́ amóhùnmáwòrán (LTV) àti ilé iṣẹ́ rédíò ìjọba ti Èkó FM àti Radio Lagos ti ìjọba yìí lẹ́yìn dé góńgó, yàtọ̀ sí èyí, owó tí wọ́n gbé fún àwọn ilé iṣẹ́ Rédíò àti Tẹlifísàn mìíràn kò níye. Ká ma fa ọ̀rọ̀ gùn, ìjọba rí owó ná lọ́pọ̀lọpọ̀ fún ẹgbẹ́ òṣèlú (APC) ju àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú yòókù lọ.

Bí ìjọba ṣe ń polongo ni ìjọba ìbílẹ̀ kọ̀ọ̀kan ìyẹn ìjọba ìbílẹ̀ mẹ́tàdínlọ́gta (57) ní Ìpínlẹ̀ Èkó ni wọ́n ń gbé e lóòyẹ̀ fún àwọn ènìyàn láti wo lójúkorojú lórí rédíò àti tẹlifísàn.

Ọ̀nà mìíràn tí wọ́n gbà lo ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán ní pípe àpèjọ àwọn olùdìbò láti máa sọ ohun tí wọ́n yóò ṣe ti wọ́n bá dórí àléèfà, eléyìí ṣíṣe lọ́pọ̀lọ́pọ̀ fún olùdíje ẹgbẹ́ òṣèlú APC Ọ̀gbẹ́ni Babajide Sanw-Olu nítorí níbi ni ó ti kọ́kọ́ la àwọn olùdíje ẹgbẹ́ rẹ̀ mọ́lẹ̀.

**d. Ìlò Owó**

Owó ṣe pàtàkì ó ṣe kókó pàápàá jùlọ nínú òṣèlú, ẹnikẹ́ni tí ó bá fẹ́ jẹ́ èniyàn pàtàkì nínú òṣèlú ó gbọ́dọ̀ ná owó pàápàá jùlọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Tí ènìyàn kò bá náwó láti ṣe òṣèĺu bí ajá ń gbó ni irú wọn. Ní Ìpínlẹ̀ Èkó ní ọdún 2007, ìjọbà tí ó wà ní orí àlèéfà ná owó gidi láti rí i pé Ìpínlẹ̀ Èkó kò bọ́ mọ́ wọn lọ́wọ́.

Eléyìí hàn gedegbe nínú ìpolongo ìta gbangba tí wọ́n ṣe, aṣọ ànkará oríṣìíríṣìí tí wọ́n tẹ àwòrán olùdìbò àti àsíá ẹgbẹ́ si ni àwọn ènìyàn wò tí wọ́n sì mú àmì ẹgbẹ́ dání ya-ya-ya, àwọn ọ̀kọrin oríṣìíríṣìí ni wọ́n gbé owó fún tí wọ́n ń fi dá wọn lárayá, ọ̀kan nínú wọn ni òṣèré onífújì ni Wàsíù Àyìndé, ibi owó tí ìjọba gbé fún un pọ̀ dé ó ṣe káséẹ̀tì jàde lórí èto ìpolongo ìbò ọdún 2007 ti wọ́n ń pín fún àwọn ènìyàn lọ́fẹ̀ẹ́.

Owó kóríyá lóríṣìíríṣìí ni wọ́n pín fún àwọn òndìbò káàkíri ìjọ̀ba ìbílẹ̀ àwọn tí ó gbà kéré jù ni wọ́n gba ẹgbẹ̀rún kan náírà. Wọ́n ṣe aṣọ iṣẹ́ fún àwọn òṣìṣẹ́ oníṣẹ́ ọwọ́ lọ́fẹ̀ẹ́.

**e. Ìlò Àǹfààní Ìjọba Orí Àléèfà**

Ẹgbẹ́ APC lo àǹfààní pé àwọn ni ó wà ní orí áléèfà láti lo àwọn irnṣẹ́ ìjọba fún ìpolongo ìbò káàkíri ìpínlẹ̀ Èkó èyí tí àwọn tí wọ́n jìjọ n polongo ìbò kò ní àǹfààní sí.

Àti ilé-iṣẹ́ rédíò àti ti tẹlifíṣàn ni ẹgbẹ́ òṣèlú AC lò láti polongo ìbò tí wọ́n sì ń gbé e jáde lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ fáráyé.

Ṣé ọ̀nà ọ̀fun ọ̀nà ọ̀run, gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ ilé-iṣẹ́ ìjọba wọ̀nyìí kò lẹ́nu láti ta ko ìjọba, wọn ṣiṣẹ́ ju ibi tí wọn rán wọn dé gan-an.

**e. Ìlò Orin Ọ̀tẹ̀ Àti Jàǹdùkú**

Gégẹ́ bí àkíyèsí òǹkọ̀wé Yorùbá Olú Owólabí (1988) tí ó sọ pé ọ̀tẹ̀ nìbò, gbogbo ìpolongo ti ẹgbẹ́ òṣèlú, òṣèlú àti àwọn yòókù ṣe ní ìta gbangba, lẹ́yìn ìgbà tí olúdìje àti bàbá ìsàlẹ̀ bá ti sọ̀rọ̀ fún bí ìṣẹ́jú bí i mẹ́wàá péré, ìyókù orin ọ̀tẹ̀ àti èébú ni wọ́n fi ń kọ, èyí sì máa ń dá ìjà sílẹ̀ ní àwọn agbègbè mìíràn tí ẹgbẹ́ òṣèlú méjì bá ti pàdé. Ní ọdún 2009, ẹgbẹ́ òṣèlú APC àti PDP ni wọ́n jẹ́ gẹ́gẹ́ bí olùfagagbága tí ó yọrí jùlọ nínú ètò ídìbò náà, àwọn nìkan ni wọ́n sì ní èrò lẹ́yìn ju àwọn ẹkẹgbẹ́ òṣèlú mìíràn bí i DPA, FP, LP., ANPP, APGA àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## Abajade Eto Ìpolongo Ìbò Ẹgbẹ́ Òṣèlú Ní Ìpínlẹ̀ Èkó

Ṣé tí ènìyàn bá tajà erùpẹ̀ dandan ni kí ó gbowó òkuta, àgbékalẹ̀ wíwọlé tipá tìkúùku tí ìpolongo ìbo àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú gùnlé lórí ní kò ṣalái ní àtubọ̀tan tí ó burú jáì.

i. **Ọ̀pọ̀lọpọ̀ Ẹ̀mí Ni Ó Ṣòfò**: Kàkà kí eku má jẹ ṣẹ̀ṣẹ́, á fi sàwàdànù ni àwọn olóṣèlú fi ṣe. Bí ẹni ń pa adìyẹ ni wọ́n ṣe pa ara wọn ní pẹẹrẹu, èyí ni bí wọ́n ṣe pa onímọ ẹ̀rọ Fúnṣọ́ Williams. Olóṣèlú yìí kò sí nínú ẹgbẹ́ òṣèlú APC, ṣùgbọ́n àtakò ńlá ni ó jẹ́ fún olùdíje yòókù nítorí pé àwọn ará ìlú tí ń gba tirẹ̀. Bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé ọlọ́pàá kò mọ ẹni tí ó pa á ṣùgbọ́n ó hàn gbangba pé lórí ètọ̀ ìdìbò yìí ni ó kú lé.

ii. **Kíkó Ìbọn Wọ Ìlú**: Ìbọn lápatì kò lápatì kò ṣéni tí í fé ká kọjú ìbọn sóhun, oríṣìíríṣìí ohun ìjà tí àwọn olóṣèlú kó wọlé lásìkò ìpolongo ìbò wọ̀nyí kò ṣe é gbà padà lọ́wọ́ àwọn ọmọ eríwo lẹ́yìn ìdìbò lára àwọn ohun ìjà wọ̀nyí ni ó jẹ́ kí olè pọ̀ káàkiri tí ó jẹ́ wí pé ọwọ́ ọlọ́pàá gan kò ká adigunjalè mọ́.

iii. **Níná Owó Ìlú Ní Ìná Àpà**: Owó tí ó yẹ kí ìjọba tí ó wà lórí àléefà fi ṣe nǹkan amáyé dẹrùn sí ìlú ni wọ́n fi polongo ibò, owó tí ìjọba ìpínẹ̀ àti ìbílẹ̀ ná sí ìpolongo ìbò ní láti ṣe ètò iná mọ̀nàmọ́ná aládaani, àti ti ti ìgbàlódé sí ípínlẹ̀ Ékó. Ṣùgbọ́n kaká kí wọ́n ṣe èyí, pínpín ni wọ́n'n pín owó fún onsdìbò.

iv. **Ẹ̀kọ́ Òdì Fún Àwọn Ọ̀dọ́**: Ẹ̀kọ́ burúkú ni ìpolongo jẹ́ fún àwọn ọ̀dọ́ nítorí pé àgbékalẹ̀ ìpolongo ìbò yìí yóò jẹ́ kí àwọn ọ̀dọ́ ní ìgbàgbọ́ pé tìpátikùúku ni wíwọlé fún ìdíje tí a bá gbé àpótí fún.

v. Rírí ìṣèlú gẹ́gẹ́ bí òtẹ̀ àti tẹ̀mbẹ̀lẹ̀kun orin ọ̀tẹ̀, asọ̀ àti èébú tí kunnú ìpolongo ìbò ju èyí jẹ́ kí ará ìlú rí ètò ìṣèlú gẹ́gẹ́ bí ọ̀tẹ̀, ó sì jẹ́ kí olùdíje rí ara wọn gẹ́gẹ́ bí ọ̀tá ara wọn. Ẹgbẹ́ òṣèlú APC tí ó wà lórí àléefà ní ìpínlẹ̀ Èkó wá rí àwọn ẹgbẹ́ òsṣèlú yòókù bí i PDP, ANPP gẹ́gẹ́e bí ọ̀tá wọn, wọn kò fún wọn ní ààyè bí ó ti yẹ.

vi. **Ìlò Bàbá Ìsàlẹ̀**: Ìlò bàbá ìsàlẹ̀ kì í ṣe ohun tí ó máa ń hàn gbangba sójú gbogbo aráyé tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n àwọn bàbá ìsàlẹ̀ bíi aṣìkò yìí dì í dì máa gbé òǹdíje káàkiri tí ó sì fi han gbogbo ènìyàn pé ẹni tí wọ́n gbọ́dọ̀ dìbò fún ni. Eléyìí ti wá di àsà báyìí tí ó jẹ́ pé ẹni tí ó bá fẹ́ kúrò lórí àléefà yóò fi ènìyàn tirè sí kódà, ó kún ojú

ìwọ̀n tàbí kò kúnjú ìwọ̀n, èyí ni ó ṣẹlè ní ìdìbò íjọba ìbílẹ̀ tí ó jẹ́ pé ìjọba ni ó yan àwọn tí ýòo díje ìbò ní ìjọba ìbílẹ̀ kọ̀ọ̀kan. Ẹni tí ìjọba kò bá fẹ́ ohun tí wọ́n ń ṣe ni pé kí wọ́n san owó tabua fún tàbí kí wọ́n dún kokò mọ́ wọn tí wọ́n ó bá fẹ́ gbowó.

vii.**Àìní Èròńgbà Kan Pàtó**: Láyé àtijọ́ ẹgbẹ́ òṣèlú kọ̀ọ̀kan ni ó ní ohun tí wọ́n mọ̀ wọ́n mọ́ tí wọ́n sì ní èròńgbà kan náà tó tí a lè fi nì ìdanilójú pé ẹgbẹ́ òṣèlú tí ó mọ nǹkan tí wọ́n ń ṣe ni wọn. Àpẹẹrẹ ni ẹgbẹ́ òṣèlú Unity Party of Nigeria (Ẹgbẹ́ Ìmọ́lẹ̀) tí Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ní ọdún 1979-1983, a mọ̀ ẹgbẹ́ yìí fún akitiyan wọn nípa

- Ẹ̀kọ́ ọ̀fẹ́ fún gbogbo ènìyàn
- Ètò ìlera
- Ètò ilé olówó pọ́ọ́kú

Ṣùgbọ́n lóde òní, a kò lè sọ pàtó pé nǹkan báyìí ni a mọ̀ tí ẹgbẹ́ òṣèlú kan yóò ṣe. àgbékalẹ̀ ìpolongo wọn kò tilẹ̀ lè jẹ́ kí ará ìlú bèèrè ìbéèrè nítorí pé tí wọ́n bá ti pín owó fún olùdìbò kò ṣòro mọ́ kálukú yóò pa ẹnu mọ́.

Lákòótán, gbogbo àléébù tí ó wà nínú ìpolongo ìbò yìí ń fẹ́ àbójútó bí bẹ́ẹ̀ kò ìgbésẹ̀ tí ìpolongo ìbò ọjoọ́ iwájú yóò gùnlé yóò burú jáì, tí a bá fẹ́ kí orílẹ̀ èdè wá jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn alágbára lágbàáyé kò yẹ kí ètò ìdìbò wa jẹ́ ẹníbáláyà-kó-wọ̀ọ́.

## Àgbálọgbábọ̀

Ohun tí a ṣe nínú iṣẹ́ yìí ni pé a yẹ ìpolongo ìbò ẹgbé òṣèlú All Progressive Congress (APC) tí ó ti pa orúkọ dà láìmọye ìgbà. A sì wo oríṣìíríṣìí ìpolongo ìbò tí ó ti wáyé sẹ́yìn ní ìpínlẹ̀ Èkó, a tún ṣíṣọ lójú ìpolongo lọ́ǹa àbáláyé tí àwọn baba ńlá wa ń ṣe kí àwọn òyìnbó tó dé, wọ́n ní ọ̀nà tí wọ́n fi máa ń polongo tí wọ́n bá fẹ́ kí oyè bó sí wọn lọ́wọ́ ní tipátipá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀nà tí àwọn olóṣèlú òde òní fi ń polongo ti fẹ̀ ṣí i nípa lílo ẹ̀rọ ìgbàlódé lóríṣìíríṣìí bí ẹ̀rọ rédíò, ẹ̀rọ tẹlifíṣàn, àwòrán olùdíje titẹ̀ sórí pàtàkì, lílo ìwé títè, ìpolongo ìta gbangba, ẹ̀rọ alátagbà àgbáyé (website), ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ohun tí a rí ni pé kò sí ìyàtọ̀ kan dàbí alárà láàárìn ọ̀nà tí wọ́n fi ń polongo ṣùgbọ́n àtubọ̀tán àkọ́kọ́ kọ̀ọ̀kan yàtọ̀ gédégbé, nítorí pé kàkà kí ewé àgbọn dẹ̀ pípele ló ń pele sí i, orin wọn kò fi bẹẹ̀ yàtọ̀, àwọn orin wọ̀nyìí so mọ ẹgbẹ́ òṣèlú kọ̀ọ̀kan, nítorí náà orúkọ ló yàtoọ̀, orin wọn kò yàtọ̀.

Kókó oríṣìírísṣìí ni àwọn orin wọn dá lé, bí àpẹẹrẹ, wọ́n ń kọrin oríṣìírísṣìí láti yin ẹgbẹ́ wọn àti olórí ẹgbé wọn, wọ́n tún ń kọrin èébú àti ọ̀tẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ orin èébú àti ọ̀tẹ̀ kìí bímoọ̀ rere, ó máa ń dá rúkèrúdò àti ìjàngbọ̀n sílẹ̀ ní gbogbo ibi tí wọ́n bá ti ń ṣe ìpolongo ìbò ni.

Ní ọdún 2007, Aṣíwájú Bọ́lá Ahmed Tinúbú tí ó jẹ́ gómìnà tí ó ń fi ipò sílẹ̀, dìídì gbé ebi tí ó fà kalẹ̀ ìyẹn Babátúndé Rájí Fáshọlá ní ibikíbi tí wọ́n bá ti lọ polongo ìbò pẹ̀lú olórin fújì wọn á sì máa kọrin èébú àti ọ̀tẹ̀ ní ibikíbi tí wón bá ti lọ polongo ìbò wọn yóò sì máa kọrin bú àwọn ẹgbẹ́ alátakò wọn. Ìgbà mìíràn, àwọn ẹgbé méjì máa ń kọlu ara wọn ní ojúkoroju, eléyìí kìi sìí bí ọmọ re, yóò dára

bí àwọn olóṣèlú bá lè wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣàdá kí wọ́n yí padà kúrò nínú jàgídíjàgan tí wọ́n dàpọ̀ mọ́ òṣèlú.

Òṣèlú tún ti wá bàjẹ́ dé bi pé tí kò bá sí bàbá ìsàlẹ̀ kò le è sí àseyọrí fún ẹni tí ó bá ń díje, eléyìí kò ń jẹ́ kí ẹni tí ó bá ní i lọ́kàn àti díje jáde, ó sì ń jẹ́ kí ẹgbẹ́ òṣèlú pàdánù ẹni rere.

Ìlò owó lọ́nà tí yóò mú ìrẹ̀wẹ̀sì bá ẹni tí ó bá fẹ́ díje fún ipò wáyé púpọ̀ nínú ìpolongo ìbò Ìpínlẹ̀ Èkó, ẹgbẹ́ òṣèlú lo owó bí ẹni pé wọ́n ń bù ú níbìkan, wón ṣe é dé ibi pé wọ́n ń ná owó fún àwọn ènìyàn ní ìjọba ìbílẹ̀ kọ̀ọ̀kan.

Lákọ̀ọ́tán, ohun ìdùnnú ni yóò jẹ́ bí àwọn olóṣèlú bá dín ìwà àfèmi-àfèmi kù nínú akitiyan wọn, nítorí pé gbogbo ìgbésẹ̀ wọn ni àwọn ọmọ tí ó ń bọ̀ lẹ́yìn ń wò tí wọ́n bá ń bá báyìí lọ, òṣèlú yóò di ohun tí ó jẹ́ wí pé ènìyàn tí ó ti ìdílé rere kankan kò ní fẹ́ ẹ́ sún mọ́ ìdí rẹ̀.

Ó yẹ kí gbogbo olóṣèlú àti ẹgbẹ́ òṣèlú tẹ̀lé ìlànà tí ìjọba là kalẹ̀ àti èyí tí ẹgbẹ́ òṣèlú kọ̀ọ̀kan là kalẹ̀.

Tí gbogbo ìlànà yìí yóò bá múná-dóko, ìjọba àpapọ̀ pàápàá gbọ́dọ̀ la ìlàná rere kalẹ̀ nítorí pé ẹṣin iwájú ni tẹ̀yìn ń wò sáré, àiṣedéédé ètò ìdìbò àti ìpolongo ìbò bẹrẹ láti ọ̀dọ̀ ìjọba àpapọ̀. Fún àpẹẹrẹ, àjọ tí ó ń mójútó ètò ìdíbò ní Nàìjíríà kò ṣiṣẹ́ rẹ̀ bí iṣẹ́ nítorí pé orin tí ìjọba àpapọ̀ bá ti da ni wọ́n ń gbé.

Ìpolongo ṣe pàtàkì púpọ̀ láti fi jíṣẹ́ fún àwọn ènìyàn ṣùgbọ́n ó yẹ kí ìlànà kan pàtó wà fún ṣíṣe èyí kì í ṣe pé kí a sọ ọ́ di ogun ati ọ̀tẹ̀.

Ọ̀làjú òde òní kò sọ pé kí orin ìpolongo ìṣèlú parẹ́ ṣùgbọ́n dípò bẹ́ẹ̀, ó tún lè gbé e lárúgẹ sí i ni. Ṣùgbọ́n ju gbogbo rẹ̀ lọ, orin ìṣèlú tí yóò bá gbé àṣà wa lárugẹ tí yóò sì buyì kún ìṣèlú orílẹ̀-èdè wa tí àwọn èwe tí ó ń bọ̀ lẹ́yìn yóò rí n rere jogún bá ni ó yẹ kí á máa kọ́ yàtọ̀ sí ọ̀tẹ̀ àti ìṣèlú bóbà-o-paá bóbà-o-bùú lẹ́ṣẹ̀.

## ÌWÉ ITỌ́KASÍ


Abraham, R. (1958). Dictionary of Modern Yorùbá, London University Press.

Alaga, B. (1986).Orin Ọ̀tẹ̀ Òṣèlú Ní Ìlú Ìbàdàn, Department of Nigerian language, St. Andrew College of Education. Ọ̀yọ́.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, A. (2007). Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lò Èdè, Òṣogbo: Tańímọ̀la Ẹ̀yìnọla Press.

CDS Abuja (1990). Ètò Ẹ̀kọ́ Fún Àwọn Olóyè Ẹgbẹ́ Òṣèlú Ní Wọ́ọ̀dù Àti Ní Ìjọba Ìbílẹ̀.

Community Focus (2006).Road to Lagos Round House 2007, Who Steps into Tinubu's Larger than Life Shoes? Moonlight Global Comm. Ltd.

Finnegan, Ruth. (1970). Oral Literature in Africa, Nairobi, Oxford University Press.

Adéyẹmí, Lérè. (2006). *Tíọ̀ri Lítíréṣọ̀ Ní Èdè Yorùbá*. Ìjẹ̀bú Òde, Shebíotimọ Publications.

Ministry of Science and Technology. (2005).The Falsification of Lagos Census Figures.

Olajubu, O. (1981). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn: Caston Press Ltd.

Olúnládé, T.A. (1994).Àbọ̀ Ìwádìí(Research Report) Apá Kìn-ín-ní, Lagos: Surety Ventures Nigeria Ltd.

Owólabí Olú (1988). Ọ̀tẹ̀ N'ibò, Lagos MacMilliam Nigeria Publication Ltd.

Raji, S. (1987).Orin Ọ̀tẹ̀, M.A. Thesis, University of Ifẹ̀.

Akhaine, S.O. (2004). Governanace Nigerian and the World, Lagos.

Ventures Nigeria Ltd.

Olómù, O.O. (2007), Ìpolongo Ìbò Ẹgbẹ́ Action Congress Ní Ìpínlẹ̀ Èkó, M.A Dissertation, Lagos State University.

Olómù, O.O. et al (2011), A Unified Standard Orthography for Nigeria, Benin and Togo CBAAC, Lagos.

Hoggart, R. (1966), *Literature and Society*, London.

Clandwell (1977), *Illusion and Reality*, London: Lawrence and Wishort.